**Akiyesi**

A nfẹ Ẹniti yio ma ha wa ta Iwe Irohin Imolẹ Ni agbegbe Ilọrin tabi Ilu miran. Ẹ kowe si ọdọ Ọgbeni: R. O. Adedeji Esq. Ni P. O. Box 12 Ilọrin

# IROHIN IMOLẸ

MOTTO: IMOLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**AKIYESI**

Ẹ ma polowo ọja yin sinu Irohin Imole

VOL. III No. 142 MONDAY MARCH 21 — MARCH 27 1960 KỌBỌ KAN (1d)


# Awon Osise Ijoba apapo ni ki won ge owo Balewa ati awon alase Ijoba (Minister) ku

AWỌN OṢIṢẸ IJỌBA TI ORUKỌ ẸGBẸ WỌN NJẸ NIGERIA CIVIL SEVICE UNION TI SỌ PE KI A GE OWO ALHAJI ABUBAKAR TAFAWA BALEWA PẸLU AWỌN ALAṢẸ IJỌBA, ATI AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ ILE ASOFIN KU, NITORI WỌN SỌ WIPE KI ILU NAIJIRIA BA LE DIN INAWO RẸ KU NI AWỌSUN OMINIRA.

Ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ yi tun sọ wipe ki a yọ owo ti Ọgbẹni Mbanefo fi kun owo awọn oṣiṣẹ Ijọba ti owo wọn ti ga laga ju tẹlẹ ri (Super Scale Officers) gbogbo ipe yi ni wọn gbimọran rẹ ti wọn si fi oke le ni ibi ipade ti wọn ṣe ni Eko ni ọjọ Jimọh ti ogunlọgọ wọn si wa nibẹ. Awọn ti wọn ṣe ipade na jẹ awọn ọmọ ilẹ Naijiria.

Ohun ti o fa idi ipade pataki ti wọn ṣe yi ni wipe Ijọba Apapọ ni awọn fẹ ṣe eto irọra na owo, ki awọn ye naa owo ni inakunna, ki orilẹ-ede Naijiria ba le ni owo lọwọ. Ipade awọn oṣiṣẹ yi wa fi ẹnu ṣe ọkan pe ki Ijọba fi ọjọ ti wọn ni wọn ma bẹrẹ irọra na owo na si iwaju, pe ki o ma bẹrẹ ni ọjọ kini osu April mọ, atipe awọn ko dẹ ni gba i gbakugba ti Ijọba fẹ fi lọ awọn yi.

Wọn ni ni iwọn igbati awọn enia Ilẹ Naijiria ti nle san owo ti o to ẹgbẹrun lọna ọgọrun mẹjọ titi de ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun fun owo ọkọ awọn Oyinbo ti o nṣiṣẹ ni Naijiria, ati ti okankan wọn tun ngba ọ g ọ r u n ọ g ọ r n u mẹrin o din ni Pọun mẹta ati ṣile mẹrinla fun owo faji, o yẹ ki Ijọba Apapọ pa owo rẹ nitori inakuna lo jẹ

Wọn tun sọ wipe Ọgbọn Pọun ti a nsan fun Oyinbo pẹlu Aya rẹ gẹgẹbi owo ẹru ti wọn ba g b a isimi lọ si ile gbọdọ parẹ, atipe ọna ti ko lọ tara ti wọn ngba lọ si ile gbọdọ duro.

Wọn ni ko yẹ, ko dẹ si tọ pe ki awọn Oyinbo ma wọ ọkọ ofuru-fu ati ti oju omi ni i p o kini lọ si ile nitori aye imiran wa ti owo rẹ ko wọn to eyi ti wọn nlo nisisinyi. Wọn ni owo to to ẹgbẹrun mẹrinlelogun ati igba o le logun ti a pese silẹ fun irin ajo awọn ọmọ ẹ g b ẹ asofin yẹ ki o parẹ ki a fi kun owo Ijọba fun nina f u n ilọsiwaju. Wọn ni adọta Pọun o le marun ti awọn alaṣẹ Ijọba ngba loṣoṣu fun owo mọto wọn gbọdọ parẹ patapata.

Wọn wa ṣe ipari ipade wọn pẹlu ọrọ yi pe ko jẹ didun inu awọn lati da rogbodiyan silẹ nipa iṣẹ ati oṣiṣẹ pẹlu Ijọba Apapọ ni awọsun Ominira, ṣugbọn o dabi ẹnipe Ijọba Apapọ lo ntọ ija, nipa pe wọn ko mọ ati ṣe eto ti o tọ.


## Ha! eti re melo?



Eyi yi ni Ẹrọ Alata to dara ju gbogbo eyi ti wọn ti nlo tẹlẹ ri lọ, lẹhin ata lilọ, o tun le lọ Igbado ati Ọka-Baba, ati Ẹwa ere orisirisi.

**£45 ni a nta** Pelu Ẹnjinni Pẹtrol tabi ati pẹlu Eletiriki Mutọ.

O WA NI ṢỌBU

**Akoshile Brothers**

5, Balogun Street West,
P. O. Box 599
Phone No. 24395. Lagos.



## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLỌWỌ FUN AWỌN ABIYAMỌ




MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ ogun pataki ta ṣe ni Aṣepe fun Awọn ọmọde, ati nlo ogun yi fun ọpọlọpọ ọdun sẹhin pẹlu idaniloju fun Awọn iṣẹ ribiribi ti o ti nṣe. MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi to dara pupọ fun igbona ikọ, otutu, Aiperi, Osi inu ọmọde, jẹdi j ẹ d i Kokoro ori ọmọde. O dara fun ọmọde ti ko tete rin ati fun awọn aisan miran bẹbẹ lọ. O nmu ki ọmọde ma nsun fọnfọn, o nmu ki ehin hihu jẹ irọ run fun awọn ọmọde. osi njẹki awọn ọmọde tobi, osi nmu wọn dan ni awọ Ẹnyin Abiyamọ, ẹku afojuba egbogi yi. Aran yin leti pe MOGBAYI BABY MIXTURE jẹ egbogi ti koṣe mani fun awọn ọmọde. Ijafara lewu pupọ, te te lọ ra ti ẹ ni ile itaja Egbogi towa ni Adugbo rẹ.

Igo kekere rẹ jẹ 2/6d Igo nla jẹ 4/6d

LILO RẸ- Sibi kekere kan lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHERS

6, Balogun Street West, Lagos Nigeria. Phone 22515

34, Docemo Street Lagos Phone 204247

# IMOLE

ESIN ỌRỌ WA-
IMỌLẸ DE OKUNKUN
PARADA

*Editorial Works & Office*
16, Bamgbose Street,
Lagos
Telephone:- 21985
United Kingdom Rep.esentative
Publishing Distributing
177, Regent Street,


## Bi o ba se emi ati ara ile mi, Ọba Oluwa ni awa yio ma sin

Ni inu iwe wa ọsẹ ti o kọja, a kede fun yin wipe ki ẹ ba Ọlọrun ṣowo, nipa kikọ ibugbe BISHOP sihu Eko ni Opopo ẸHIN IGBE TI, pupọ ninu nyin le ma bere kini ipin ti awa Oniwe Irohin Imọlẹ ti o fi le bayi.

Gbogbo wa lo mọ dajudaju wipe Irun Imu lowo koṣe yara fatu, ẹnikẹni ti o ba si ni ipin nipa Ọrọ Ọlọrun, daju ile rẹ ati gbogbo ọna rẹ yio ma gun regerege ni.

Awọn Olotu Ikọle na fi nye wa wipe ninu oṣu to nbọ lagbara Ọlọrun, awọn yio yan enia ti yio ma kakiri lati gba owo ẹbun. Ẹnyin onkawe wa nibikibi ti o ba wa ni o ma le fi ẹbun owo tirẹ na ranṣẹ yala si alufa Ṣọṣi rẹ tabi si Bishops Court Ọdunlami St. Lagos. Gbọ ni agbọye ẹnikẹni ti o ba fi owo ti o to Pọun marun- sile marun ranṣẹ, orukọ Oluwarẹ yio jade lara okuta ti nwọn yio kọ si ara ile na, niti awa Irohin Imọlẹ awa nfẹ ki Orukọ wa ki o han nile Ọlọrun.

Iwọ ti o fi Pọun marun sile marun ba Ọlọrun ṣowo, ainiye ọna ni Ọlọrun rẹ yio fi san fun ọ ati fun irandiran rẹ. Awa fẹ ki ẹ mọ daju wipe enia ti kiṣe enia dudu fun wa ni apo owo meji ati abọ, (£250) ki ṣe ilu wọn ni ao kọ ile na si, bẹ si ni ki ṣe on ni yio kọ ile na fun ara rẹ, ṣugbọn o ranti wipe ẹnikẹni ti o ba ba Ọlọrun ṣowo ko ni padanu rara. Nitorina awa fẹ ki olukuluku nyin ti ẹ jẹ okawe wa ba Ọlọrun yin ṣowo ki ẹ si wo ire ti yio fi san fun yin ati irandiran yin, bi o ṣe tọrọ ni o ni, bi o si jẹ pọun kan ni, ko si eyi ti o buru, bi o ba si pe lori iṣẹ ti o nṣe, tọrọ pere tabi pọun kan pere ni, o tọ si ọ lati fi ba Ọlọrun ṣowo ṣugbọn awa fẹ ki ẹ mọ daju pe ti adanwo ba de ba wa, ko si ẹniti ao kigbe bi ko ṣe Ọlọrun wa na, ti Ọlọpa ba mu wa loju kan na, ao na owo ti o ju Pọnun meji lọ, ti ao ba si bọ ninu rẹ na, Ọlọrun na ni ao kigbe pe Tọtọ Ọlọrun ki ngba owo ṣugbọn o npese owo fun wa awa si rope owo wa lati fi tun ọna RẸ ṣe.

### Ẹ BA ỌLỌRUN YIN ṢOWO PỌ

A fẹ ki enyin okawe wa mọ eyi daju pe ile Bisọbu ti ao kọ yi kiṣe ohun ini ti Bisọbu tabi ti Ọgbẹni Bisọbu Howells tabi ti Alufa kan, Ọmọ tirẹ tabi ọmọ tẹyin le de Ipo Bisọbu ni ọla ile yi ti ao kọ yi wa fun Bisọbu ki Bisọbu ti o ba wa lori oye BISỌPU.

## Aboyun kan ku si odo Oya

Aboyun kan ku si odo Oya ni lọkoja ni ọsẹ to kọja. Ohun ti o fa idi iku rẹ ni pe ọkọ ti on pẹlu ọkọ rẹ ati awọn ọmọ rẹ meji wọ kọlu iṣan nla kan ọkọ na si yi biri, lo ba da wọn somi. Ọkọ rẹ sa gbogbo ipa lati ri pe aya on pẹlu awọn ọmọ ko ri, Ṣugbọn awọn ọmọ rẹ mejeji nikan ni agbara rẹ ka lati gba la, aya rẹ si ri o ku.

Wọn ti gbe oku Aboyon yi lọ si ile-iwosan fun li-la lati wadi ohun ti o pa a, a dẹ gbọ wipe wọn ko ni pẹ sin oku rẹ.

OWE ILE-YORUBA :- Aitọ̃ ehin ika, ni a nfi owọ boo Ari gbe 'yawo ko to pọn, Owo Ọbẹ l'o ṣoro. Owo ko si mọ, Enu ọkọ di ẹru di ti a ka. Aya a ngbẹ ni ki o ṣe tan ki o ngb'nu wa ma wa jẹun

## IDIJE! IDIJE!

A fi eyi kede fun awọn Onkawe Irohin Imọlẹ ati awọn Ọmọ karọ -o- jire pe a nfẹ

### ITAN LEDE YORUBA

Eyiti ẹnikẹni ko ti tẹ jade ninu iwe ri tabi ti wọn ko ti sọ lori Radio ri ẹnikẹni ti o ba si bori yio gba.

**(£1 1s.)** PỌUN KAN SILE KAN.

Akiyesi:- Kọ itan ki o han rekete, ti ẹniti ko ba han a o fa ya ni, ki o si mọ dajudaju pe ko ni ipa ninu Idije na ti ITAN ẹniti o basi daraju ni ao tẹ jade ninu Iwe Irohin Imọlẹ yi a o si fi (£1: 1s-) Postal (Order) ranṣẹ si Akọ kọ Ọmọde tabi agbalagba Fi Stamp Tọrọ (3d) ranṣẹ fun gbigbe Pọun kan Sile kan (£1: 1s) ti o ba jẹ pada si ọ, ki o ge ibiti Idije yi wa, ki o si fi ranṣẹ pẹlu Stamp tọrọ rẹ si wa, ẹnikẹni ti ko ba ge Idije tirẹ ranṣẹ siwa, ti o ba jẹ owo na, akọ ni fi ranṣẹ si, a ko si ni fun ni Stamp Tọrọ rẹ,

Orukọ ______________________

Ibugbe. ______________________

______________________

Iṣẹ. ______________________

Ọjọ Ori. ______________________

Fi itan rẹ ranṣẹ si:-

OLOTU IROHIN IMOLE
16, BAMGBOSE STREET LAGOS.


## Yan ọrẹ kan!

fi siga **GALLEON**

TI NAIJIRIA NFẸ Ṣ'ALEJO

o ndun bi olowo-nla
...owo rẹ si kere pupọ
kọbọ kan fun
ẹyọ kan
**1'8 fun 20**



# NIPA ISLAM

Lati Qwọ:— ALUFA HUSAEN MUHAMMAD.
No. 10A. Thomas Street Lagos.

## Ibere lori Esin re

IBERE: Lati ọwọ Ogunṣọla, Shogunle: "Alufa ohun ti gbagbọ tẹlẹ ni wipe Ọlọrun ko fẹ ọti m i m u rara, sugbọn owa yanu lẹnu lati ma gbọ ni ẹnu awọn Kiriyo wipe amupara ni Ọlọrun kọ. Ẹjọwọ ṣẹ alaye ọ r ọ na fun mi pẹlu ẹri ninu Bibeli.

IDAHUN:- Ohun ti o ma koko fi mọ pe irọ ni wọn npa ni wipe niwọn iba igba ti ati mọ pe Ole jija kodara, ko wa si ẹniti o le fi ye wa wipe jija wara ni ofin kọ; Bi o ba si wa ni Bibeli lọ w ọ ki o gbiyanju lati wo awọn aye won yi fun ẹri ti o daju:- Lifitikus ori: 10 ẹsẹ 9, ati Aisaya ori 5 ẹsẹ 22.

IBERE: Kini anpe ni Jaka?

IDAHUN Ohun ti anpe ni Jaka ni sara ti Ọlọrun ṣe ni ọranyan fun gbogbo Musulumi lati ṣe ni owuro ọjọ ọdun itunu, pẹlu onjẹ ti oba wọpọ ju ni ilu ẹni Ki o le jẹ amin oju anu ati inu rere si awọn alaini

IBERE Nigbawo ni oyẹ ki enia yọ saka ninu dukia eni; nitori ti mo ri pe inu awẹ nikan ni awọn enia ma nṣe eyi.

IDAHUN Enia lati yọ saka ninu dukia rẹ nigbati oba ti pe ọdun kan gbako ti da iṣẹ tabi owo rẹ silẹ, kiba wa jẹ inu awẹ tabi igba omiran lo bọ si, sugbọn ohun ti inu awẹ fiwa wọpọ ju nipe alubarika ti oṣu na lori sara ṣiṣe gbogbo pọ ju ti ọpọlọpọ oṣu toku lo.

IBERE Njẹ ọranyan ni ki enia ma lọ si MEKKA ni ọdọdun?

IDAHUN kise ọranyan ni ti ọdọdun, ti akoko lọ enia ni o jẹ ọranyan.

IBERE Njẹ odara ki enia ma ki irun ọdun ninu ile rẹ pẹlu ohun ori redio.

IDAHUN Eyi ko bọ si rara. Oni lati fi ẹsẹ ara rẹ rin lọ ehin odi lati lọ fi ihin ati ọpẹ fun Ọlọrun, niwọnba igba ti o ko ba ti si ni ori ailera.

Otun di ọsẹ to mbọ. Oluwa ko ṣe ọdun ni abo fun wa o.



# MA SO IRETI NU RARA O

Bere awọn ojulowo egbogi Jamani ati orisirisi ilu miran wọnyi pataki ni fun 'AJO' tabi 'ITOJU' Obinrin tabi Ọkunrin ti ọko ati iyawo ti o daju. Meji iru wọn ko si ni gbogbo ṣọbu ni igboro ilu Eko.



Ekini:- Egbogi ti a npe ni ERMELINDA fun Obinrin orisi mẹta lo wa ninu P a l i rẹ, o pa bambari fun ajo tabi idiwọ, Adota sile (50/-) ni owo pali kan jẹ, owo ọkọ 3/6d. Ekeji:- Egbogi ti a npe ni SANURSEX fun Obinrin Ṣilemejilelọgbọn pẹlu sis. (32/-6d) owo ọkọ 2/6

Ẹkẹta:- Egbogi ti a npe ni OPO-JOVEN fun Obinrin (ojulowo Egbogi Awọn Farase) Ṣilemejidinlogun abọ 18/6d owo ọkọ 3/6. Ẹkẹrin:- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN fun obinrin Ṣilemẹrinla abọ 14/6 owo ọkọ 2/-

Ẹkarun:- Egbogi ti a npe ni FANDORINE fun obinrin (Egbogi Faranse) Ṣilemẹrila-abọ (14/6d) owo ọkọ 2/ Ẹkẹfa: Egbogi ti a npe ni OSTORPIROS fun obinrin ṣilemejọ-abọ (8/6d) owo ọkọ ṣilekan pere (1/-)

OJULOWO EGBOGI FUN AJO ILERA TI ỌKUNRIN

Ekini Egbogi ti a npe ni SANURSEX Ọgbọnṣile (30/- Igo nla owo ọkọ 3/- Ekeji:-Egbogi ti npe ni TESTONIC Pọwun-kan £1 igo kekere mewa-abọ owo ọkọ 2/- Ẹkẹta:- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN ṣilemejila-abọ (12/-6d) owo ọkọ 2/- Awọn egbogi wọnyi lagbara gidigidi wọn si nṣiṣẹ ribiribi fun awọn ti wọn nlo wọn pẹlu wọn ko dabi awọn egbogi rọbirọbi ti wọn nta kakiri wọn yatọ patapata o si daju pẹlu.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orisirisi amodi ti o ba fẹ ni ṣọbu awọn:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palm Church Street, P. O. Box 333**
**Lagos Nigeria Phone 22878**
**Ati Pelu Ni Sobu Arabinrin.-**

MRS. C. O. BABAJIDE,
NEAR HEALTH OFFICE IBADAN
ati ni ABIMBOLA MEDICINE STORES
B29 Okesha Street, Ilesha
BISALE MEDICINE STORES
BRITISH & FOREIGN MEDICINE (DEALER)
S W 6/456 AGBOKOJO STREET, IBADAN, N.

AKIYESI:— Ri daju gbangba wipe sọbu ti wọn nta lo gbe ranṣẹ lọra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọta adamọdi tabi orisi omiran fun ọ o, maṣe gba rara.

## Iwe ilana Ifa, Yanrin tite, Etutu Sise, Iwosan ati Egbogi Ajebidan.

Ti o ba ni Iwe yi lọwọ- Oṣo Aiye, Ajẹ Enia- majeki Tẹnisu wọn, Alapeta ati awọn ibaba ati ikoko ko ni lagbara lori rẹ Ohunkohun ti o ba dawọle rere ni yio ma jasi Babanla Awure ati Ogun Ajẹbidan wa nibẹ pẹlu tete ni tire ki o to tan, awọn Babalawo papa nwa dura lọdọ wa ni. Iye Owo 10/6d.

2 Itumọ Ala ati Ayẹwo Odu Ifa 2 6d.
3 Agbara Igba Iwaṣẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 3/-
4 Gbedegbeyọ Hausa 2/6 5. Itumọ Ami Ara 3/-
6 Ewọ Yoruba ati Etutu 3- 7. Ma fọmọ y ọ m i (Arofọ 1/6d Turari Itaja Adura Tetedamilohun, ati Iṣegun Ajẹ pẹlu Psalmu Ajẹbidan 15/6.

Fi Owo ranṣẹ si Ọgbẹni J.O. Shoyinka 6, Ojo Road, Oduabọrẹ Mushin.

# MA FI OWURO S'ERE APA 8

Lati Owo' J. O. SHOYINKA (Mushin)

Akiyesi :- Mo be enyin oluka itan mi jakejado ilę Naijiria pe kę ma binu pe itan mi ko jade lọsę to kọja, aiko raye kọn ni. Lagbara Oluwa ẹ o ma ri ka lọsọsę nisisinyi niwọn igbati mo ba si nmi. Ę ku orugbo, ę ku isę ore o, emi a sika o Amin.

## AWỌN ỌMỌ ERINWO ŞA NI IŞAKUŞA

Lọgan ti Mafarọsere ti paşę pe ki nwọn pa Omiran yi ni ipakupa, işeju aya wọn ko ake boo, pa pa. pa, wọn si şa to'ri lọrun, jagun lulę wongangan bi gẹdu, o kigbe too, bayi ni o si fi ku finrinfinrin.

Nigbati awọn ọmọ erinwo mu aşę Mafarọsere şe tan, onipesę jẹ olukuluku wọn, nwọn wa nwoye. Nigbana Mafarọsere wa di de ganran, o ni ę ku ijoko enyin arakunrin mi a ja ogun kekere a si molu, ogun nla nbọ niwaju wa ti a o ja nko mọ ero ọkan ti nyin, nitoripe ibi ni a ba nyin. Ohun ti o si le olukuluku de ibi ọtọtọ ni, şugbọn bi o se emi ati awọn enia mi ni o, a ko beru enia a fi Ọlọrun ọba," dajudaju ao kolu eniti o ba kolu wa, enikeni ti o ba bağwa ja, a'o ba ja dọba, bi enia kan ju okuta ba wa a o ju idarọ lu u. Omiran ba wa şe o mọ ọ ti, anbọsibọşi abirun enia kan lasanlasan Enyin arakunrin mi, ohun kan ti o ku ti a nilati se nisisiyi niki a wa ọna ti ao gba fi jade ninu ọgbun iparun yi. Ẹnję, a mmu nigbati akoi ti pa Onibode ati Omiran. Nigbati a pa wọn tan, kini o ku ti a lę jẹ, lotitọ onjẹ diẹ şi wa nilę. Şugbọn ti gbogbo wa ba beresi jẹ ki o to to ẹwọyi ọtunla yio tan bamubamu, nitorina ni mo şe sọ pe ọna ti a o fi yọ kuro ninu ahamọ yi ni ki a ma wa. Enyin ara mi tani o mọ owọ yi pada ninu nyin?

Wọn beresi wo ara nwọn loju, nitoripe ede ti Mafarọsere pe ko yewọn. Ọkan ninu wọn ti [illegible] ọkunrin [illegible] Mafarọsere pe alagba itumo ọwọ yi yipada Mafarọsere rerin musen, o ni atumọ eyi ni ni pe tani mọ egbogi ajẹbidan ati ayajọ ti o daju hantaun Oloburo yi papa wa mi kanl ę on papa rerin musen o ni bi o ba jẹ baun ni, emi gonta bi imi ori akitan yi ko kere ninu ogun nitori odę gidi haun ni emi işe ki nto de ibin Mafarọsere dupę lọwọ re o ni areni fi işę na le lọwọ.

Marọsere tun bere oruko rę o ni nitoripe iki ba ni rin ka ma mọ orukọ eni. Ọkunrin na si dahun, o ni AKỌOKUIA ni oruko mi nję.

Akiyesi:- Ni ọsę to nbo lagbara Oduae e o ma ka apa (9) ati bi wọn ti se jade ninu ọgbun buburu yi.

## Ikede Pataki

A fi eyi şe ikede fun enyin onkawe wa wipe opolopo enia lo ti fi itan Idije tire ranşę ti ko fi Stamp toro (3d) sinu rę, enikeni ti o ba fę ma pe on ti fi itan ti on ranşe, ti on ko si fi Stamp toro sinu itan on, ki o tete ko omiran, ko si fi ranşe pelu Stamp toro (3d) nitoripe a ti fa ti akoko ti ko si Stamp toro (3d) nibe ya. Itan gbigba yio pari ni ojo kerin Osu april 1960 4/4/60 enia ti o fi tire ranşe lehin asiko ti a dawọko yi, a ko ni gba mọ.

OLOTU

dvert No 26

## PUBLIC HOLIDAYS 1960

With reference to advertisement NO. 26, published in this newspaper on the 14th of March 1960, the Public Holiday in celebration of the Muslim Festival of Id-el Maulud this year will be on Monday, September 5th and not on Monday the 6th of September.

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street, Lagos Phone: 21965
Olotu: E. A. Ademi No. 51, Tejuosho Street Surulere, Yaba
FUN OWO "IROHIN IMOLE" ỌDUN KAN EKO— Şile Mẹrin ati Kọbọ Mẹrin (4/-4d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun, Şile Mẹfa ati Kọbọ Mẹfa (6/-6d.)

# şile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Şile kan pere ni owo rira rę, koro egbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rę. Nisisiyi, enikeni le ni "ASPRO" ni ipamọ sọwọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kolu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura silę. Ra pakẹti "ASPRO" titun oni şile kan loni!

## 'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO